# IFIHÀN TI JESU

## Ifihan 1:1-20.

## ẸKỌ 459 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Kiyesi i, o mbọ̀ ninu awọsanma; gbogbo oju ni yio si ri i, ati awọn ti o gún u li ọ̀kọ pẹlu; ati gbogbo orilẹ-ede aiye ni yio si mã pohùnrere ẹkún niwaju rẹ̀" (Ifihan 1:7).**

**I Awọn Ikede Ti A Ṣe Fun Johannu**

1. Ọlọrun fun Jesu ni iṣipayá awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ ni lọọlọọ a si ti ipasẹ angẹli kan fi han Johannu, Ifihan 1:1 2 Tẹssalonika 1:7, 8
2. Johannu jẹri si ohun gbogbo ti o ri, Ifihan 1:2
3. A gbà wa niyànju lati ka awọn ọrọ wọnyii ati lati pa wọ́n mọ́, nitori igba kù si dẹ̀dẹ, Ifihan 1:3

**II Iṣẹ Ti A Rán Si Awọn Ijọ Nipa Bibọ̀ Rẹ̀**

1. Si awọn ijọ meje, ti i ṣe apẹẹrẹ Ijọ Rẹ̀, ni a rán ọrọ Iwe naa si, Ifihan 1:4, 11
2. Kristi, Ẹni ti yoo wá bi Ọba, ti gbà wá là, O ti sọ wa di mimọ́, O si ti ṣe wa ni ọba ati alufaa, Ifihan 1:5, 6; Efesu 5:25-27
3. Gbogbo eniyan lati ọjọ iwà ni yoo ri agbára ati ògo Oluwa, Ifihan 1:7, 8

**III Ẹni Iyanu**

1. Johannu gbọ́ ohùn kan ni ẹyin rẹ̀ o si yi pada lati ri Ẹni ti n sọrọ, Ifihan 1:10, 12
2. A ṣapejuwe aworan ẹni ologo ti Johannu ri, Ifihan 1:13-16; Daniẹli 7:9-14
3. Kristi jẹri nipa ara Rẹ̀, Ifihan 1:17, 18
4. Ohun ijinlẹ ti irawọ meje naa, ati ọpa wura fitila meje naa ni a fi hàn, Ifihan 1:19, 20

## ALAYE

**A Wà á Lọ Si Patmo**

Johannu, Apọsteli ayanfẹ nì, ni ẹni ti o kọ Ifihan eyi ti a rò pe a kọ niwọn ọdun mẹrindinlọgọrun lẹyin ibi Kristi. Johannu jẹ́ arugbo nigba ti ọba Romu, Domitiani, wà á lọ si Erékuṣu Patmo, "nitori ọ̀rọ Ọlọrun, ati nitori ẹri Jesu Kristi." Gbogbo awọn Apọsteli iyoku ni o ti jiya ajẹrikú ṣiwaju akoko yii, o tilẹ le jẹ pe Johannu nikan ni o kù lara awọn ti wọn ri Jesu lojukoju ti wọn si ti gbohùn Rẹ̀ nigba ti o wà nihin ninu ayé. Oluwa fun un ni iṣipaya awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ nikẹyin ọjọ titi dé igba bibọ̀ Jesu lẹẹkeji ati ayọ̀ iṣẹgun ikẹyin lori agbára awọn ọta.

Patmo jẹ́ ibi olokuta kan laaarin awọn akojọpọ Erekuṣu Griki, niha guusu iwọ-oorun ilu Efesu. Kò ni eweko, tabi odo, tabi ilẹ fun ohun ọgbin rara. O jẹ́ okiti aṣalẹ olokuta kan ṣá, awọn ọdaran ti a lé kuro nilu ni a maa n wà lọ si ibẹ̀. Fun Johannu, inunibini lati Romu ṣi ọna isopọ mọ́ Ọrun ti o ga jù lọ silẹ. Nigba pupọ ni ibinu awọn eniyan buburu maa n mú awọn eniyan mimọ́ wá sinu irẹpọ timọtimọ pẹlu Ọlọrun.

**Iwe Iṣipaya**

Itumọ Iwe Iṣipaya ni ohun ti a fi hàn. Ẹsẹ kin-in-ni n sọ fun wa pe Ọlọrun fi ifihàn yii fun Jesu Kristi lati fi han awọn iranṣẹ Rẹ̀ ohun ti ko le ṣai ṣẹ ni lọọlọọ; O si ranṣẹ, O si fi i hàn lati ọwọ angẹli Rẹ̀ wá fun Johannu iranṣẹ Rẹ̀.

Gẹgẹ bi iwe Gẹnẹsisi ti n sọ itan iṣẹdá ayé ati ileri akọkọ nipa Olugbala araye, bẹẹ gẹgẹ ni Iwe Ifihan, ni ipari Bibeli, n kede opin eto isisiyii, o si tun n fi ogo ati ọlanla Kristi ni igba ipadabọ̀ Rẹ̀ lẹẹkeji hàn. Kókó ori Iwe yii ni iṣẹgun nla ti Ijọba Ọlọrun. A n sọ fun ni pe o jẹ́ afárá ti o dabu alafo nla ti o wà laaarin wiwá Jesu ni akọkọ ati bibọ̀ Rẹ̀ ni ẹẹkeji.

"Olubukún li ẹniti nkà, ati awọn ti o ngbọ́ ọ̀rọ isọtẹlẹ yi, ti o si npa nkan wọnni ti a kọ sinu rẹ̀ mọ́" (Ifihan 1:3). Ọpọlọpọ ni wọn ka Iwe Ifihan si Iwe ti a lẹ̀ pa, wọn kò si gbiyanju lati ni òye rẹ̀, ṣugbọn Iwe Mimọ́ ní "Olubukún" ni awọn ti n kà á, ti wọn si n pa á mọ́. O si tun wi pe Ọlọrun fi i fun Jesu ki O le fi han awọn

iranșẹ Rẹ̀.  Ohun pupọ ninu Iwe naa ni a kọ lati fi ṣe aworan ati apẹẹrẹ, sibẹ ọ̀pọ ninu awọn ileri ti o niyelori ju lọ ninu Bibeli ni a fun ni ninu Iwe yii.

**Ìkíni**

Ìkini yii jẹ́ lati ọdọ Johannu si ijọ meje ti o wà ni Aṣia.  "Ore-ọfẹ fun nyin, ati alafia, … lati ọdọ Jesu Kristi, ẹlẹri olõtọ, akọbi ninu awọn okú, ati alaṣẹ awọn ọba aiye,  Ẹniti o fẹ wa, ti o si wẹ wa ninu ẹ̀jẹ rẹ̀ kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa, ti o si ti fi wa jẹ ọba ati alufa fun Ọlọrun ati Baba rẹ̀; tirẹ̀ li ogo ati ijọba lai ati lailai" (Ifihan 1:4-6).  Wo iru ikini nla!  O ti ori ikini lati inu igbona ọkàn wá bọ́ si ori iyin alayọ: "Tirẹ̀ li ogo ati ijọba lai ati lailai."

Oore-ọfẹ ati alaafia lati ọdọ Ẹni ti O fẹ́ wa ti O si wẹ̀ wá nù kuro ninu awọn ẹ̀ṣẹ wa nipa Ẹjẹ Oun tikara Rẹ̀!  Bi Oun bá fẹran awọn ọta Rẹ̀ to bẹẹ ti O fi kú fun wọn lori agbelebu, bawo ni ifẹ Rẹ̀ yoo ti pọ̀ tó si awọn ti a ti rapada nipa Ẹjẹ Rẹ̀ iyebiye!  Eyi fi hàn daju pe Ẹjẹ Rẹ̀ n wẹ awọn ẹ̀ṣẹ wa nù.  Eredi rẹ̀ gan an ti O fi wá gẹgẹ bi Ọmọ-ọwọ Bẹtlẹhẹmu ni lati kú lori agbelebu ati lati ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun igbala ayé ti o ti sọnù.  Awọn wọnni ti o gba igbala nla yii kò bọ́ ninu ẹ̀ṣẹ wọn nikan, ṣugbọn a fi wọn ṣe ọba ati alufaa fun Ọlọrun pẹlu.  Rò o wò!  Lati ipo irẹlẹ ayé ki a wa jẹ́ ọba ati alufaa fun Ọlọrun!  "Enia iba ma yin OLUWA nitori ore rẹ̀, ati nitori iṣẹ iyanu rẹ̀ si awọn ọmọ enia!" (Orin Dafidi 107:8).

**O N Bọ̀ Ninu Awọsanma**

"Kiyesi i, o mbọ̀ ninu awọsanma" (Ifihan 1:7).  Nigba ti Jesu fi ayé yii silẹ awọsanma gbà A kuro loju awọn ọmọ-ẹyin.  Nigba ti O ba tun n pada bọ̀, yoo jẹ́ ninu awọsanma, ninu ara ti a o fi oju rí.

Awọn olukọni miiran n fẹ sọ fun ni pe wiwá Rẹ̀ sinu ọkàn ni a n pè ni bibọ̀ Rẹ̀ lẹẹkeji.  Johannu ti ri Jesu nigba ti O n rin lori ilẹ bi eniyan; lẹyin naa bi Kristi ti o jinde ki o to goke re Ọrun.  Ni gbogbo ọdun wọnni lati igba ti Jesu ti pè e lati jẹ́ ọ̀kan ninu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, ni ifẹ Jesu ti n gbé inu ọkàn rẹ̀; nisisiyii Johannu n ri I bi O ti wà ninu ogo Rẹ̀.

Jesu tun n pada bọ̀ gbogbo oju ni yoo si ri I.  Fun awọn kan yoo jẹ́ iriri ologo, awọn ẹlomiran yoo si maa ké pé ki okuta ati awọn òkè ki o fi wọn pamọ.  Ẹsẹ yii ni ori kin-in-ni Ifihan sọ pato nipa awọn ti o gun Un lọkọ̀, awọn ti o kan iṣo mọ́ ọwọ́ ati ẹsẹ̀ Rẹ̀, ẹni ti o fi idà gún ihà Rẹ̀, pẹlu awọn wọnni ti o kigbe pe, "kàn a mọ agbelebu, kàn a mọ agbelebu."

**Ọjọ Oluwa**

Johannu ni oun wà ninu Ẹmi ni ọjọ Oluwa, ọjọ ti awọn Onigbagbọ́ maa n pejọ pọ̀ lati ṣe iranti ajinde Oluwa, ọjọ ti iṣẹlẹ ti o ṣe ribiribi ju lọ laye ti yà sọtọ titi lae.  A ti ya ọjọ keje si mimọ́ a si ti n pa a mọ́ ni iranti Iṣẹda Ayé, o si jẹ́ Ọjọ-isinmi awọn Ju.  Awọn Onigbagbọ́ n pa ọjọ kin-in-ni ọsẹ mọ́, ọjọ ti Kristi jinde, ni iranti Irapada.  Eyi ni Ọjọ isinmi Onigbagbọ́ (Wo Ẹkọ 268, ninu Iwe 21).

**Fifun Ipè**

Johannu gbọ́ ohùn nla kan lẹyin rẹ̀ bi iro ipè.  A maa n fun ipè nigbakuugba ti iṣẹlẹ nla bá ṣẹlẹ.  O pẹlu ohun ti Ọlọrun lò lati fi ara Rẹ̀ hàn.  Nigba ti Ọlọrun fi ara Rẹ̀ hàn lori Oke Sinai, O fi ohùn ipe ti n dún kikan-kikan mu idakẹrọrọ kuro.  Nipa fifun ipe fadaka ni a fi n kede didé Ọdun Jubeli.  Ohùn olori angẹli ati ti ipe Ọlọrun ni yoo fọ́ idakẹrọrọ ipo-oku ti yoo si kó awọn ayanfẹ Ọlọrun jọ lati ipẹkun ayé.  Awọn ẹni-ayé ti kò ni Ọlọrun le ṣai gbọ́ didún ipè yii, ṣugbọn awọn ti a ti fi Ẹjẹ Jesu wẹ̀ mọ́ yoo gbọ́ ohùn ipè a o si pa wọ́n lara dà, wọn o si fi ìyẹ́ fò lọ bi idi lati pade Oluwa wọn ni awọsanma.

**Ọpa Fitila Meje**

Nigba ti Johannu yi pada lati wo Ohùn ti n bá oun sọrọ, o ri ọpa fitila wura meje, ati laaarin awọn ọpa fitila naa ẹnikan ti o dabi Ọmọ-eniyan.  Awọn ọpa fitila meje ni duro fun awọn ijọ meje ti o wà ni Aṣia.  Awọn ọpa fitila jẹ́ ohun ti n gbé imọlẹ duro.  Wọn kò ni imọlẹ ninu ara wọn ṣugbọn awọn ni n gbé imọlẹ ró.  Jesu ni Imọlẹ tootọ.  Ijọ ni o n gbé Imọlẹ tootọ lọwọ, olukuluku Onigbagbọ́ atunbi si n jẹ ki imọlẹ rẹ̀ tàn nipa ẹri rẹ̀ ati nipa igbesi-ayé rẹ̀.  Awọn ọpa fitila naa jẹ́ ti wura eyi ti i ṣe ohun ti o niyelori pupọ ninu ohun ti a n mú jade lati inu ilẹ.  Awujọ awọn eniyan mimọ́ ni o ṣe iyebiye ju lọ ninu ayé yii.  Oun ni wura gidi ti ayé.

**Ọmọ-Eniyan**

Ori ati irun Rẹ̀ dabi ẹgbọn owu, o funfun bi sno.  Iwe-Mimọ́ sọ fun ni pe ade ogo ni ori ewu bi a ba ri i ni ọ̀na ododo (Owe 16:31).  Ẹsẹ̀ Rẹ̀ dabi idẹ daradara, bi ẹni pe a da a ninu ileru.  Ẹsẹ̀ mimọ́ yii ni Oluwa fi n rin

laaarin ijọ, gbogbo irira ni Oun yoo si fi ẹsẹ̀ fọ́ luuluu. Daradara ni ẹsẹ̀ wọnni fun awọn ti o fẹ Ẹ, ṣugbọn ẹ̀ru jẹjẹ ni fun awọn wọnni ti a o fi tẹ̀ mọlẹ.

Ohùn Rẹ̀ dabi iro omi pupọ. Yoo ha ṣe le yatọ? Ni ọjọ kan Ohùn naa yoo jí awọn oku. "Ohùn OLUWA li agbara; ohùn OLUWA ni ọlánla" (Orin Dafidi 29:4).

O ni irawọ meje ni ọwọ ọtun Rẹ̀. Irawọ meje naa ni awọn angẹli tabi awọn alufaa ijọ meje naa. Kristi n rin laaarin awọn ọpa fitila naa ṣugbọn O di awọn alufaa wọnyii mú pẹlu ọwọ ọtun Rẹ̀.

Lati ẹnu Rẹ wa ni idà oloju meji mimú ti jade. Bibeli sọ fun wa pe: "Ọ̀rọ Ọlọrun yè, o si li agbara, o si mú jù idak'ida oloju meji lọ, o si ngúnni ani titi de pipin ọkàn ati ẹmi niya, ati orike ati ọrá inu egungun, on si ni olumọ̀ ero inu ati ète ọkàn" (Heberu 4:12). "A rẹ́ idà mi li ọrun, kiyesi i, yio sọkalẹ wá sori Idumea, ati sori awọn enia egún mi, fun idajọ" (Isaiah 34:5). Oju Rẹ̀ dabi oorun ti o n fi agbara rẹ̀ ràn. Awọn ijọ ni fitila, awọn alufaa ni irawọ; ṣugbọn Kristi ni oorun naa.

Iru iran bẹẹ ni awọn ọmọ-ẹyin mẹta ri nigba ti a pa Jesu lara dà loju wọn lori Oke. "Oju rẹ̀ si nràn bi õrùn, asọ rẹ̀ si fún, o dabi imọlẹ" (Matteu 17:2).

**Ọrọ Itunu**

Titobi ati ẹlẹru ni ogo, ati agbára, ati iyanu, ati ọlanla ti Johannu ri. Oniwe kan ṣapejuwe rẹ̀ wi pe: "Iro ipe, iran ologo, oju iṣipaya, ohùn agbara, oju itanṣan imọlẹ …"

Iran naa tobi to bẹẹ ti Johannu fi wolẹ lẹsẹ Kristi bi ẹni ti o kú. Jesu fi ọwọ ọtun Rẹ̀ le e O si wi pe, "Máṣe bẹ̀ru". Ọrọ itunu!

**AWỌN IBEERE**

1. Erekuṣu wo ni a wa Johannu lọ? Ṣe apejuwe rẹ̀.
2. Ki ni ṣe ti a wà á lọ sibẹ?
3. Ọjọ wo ninu ọsẹ ni Johannu ri iran yii?
4. Ki ni ṣe ti awọn Onigbagbọ fi n pa ọjọ yii mọ́?
5. Ki ni awọn ohun ti Johannu kọkọ ri ninu iran naa?
6. Ki ni wọn duro fun?
7. Darukọ awọn ijọ meje ni Aṣia ti a rán iṣẹ yii si?
8. Ṣe apejuwe irisi "Ọmọ-enia."
9. Bawo ni iran ti Johannu rí yii ti mú un lọkàn tó?

Ki ni Jesu wi fun un?